# AJINDE ATI IGOKE-RE-ỌRUN KRISTI

## Marku 15:42-47; 16:1-20; Iṣe Awọn Apọsteli 1:1-11.

## ẸKỌ 435 -- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Ẹ lọ si gbogbo aiye, ki ẹ si ma wasu ihinrere fun gbogbo ẹda" (Marku 16:15).**

### Ireti Pin

Fun ọpọlọpọ ọgọrun ọdun ni awọn Ju ti n foju sọna fun ẹnikan ti yoo dide laaarin wọn ti yoo si jẹ ọba nla. Wọn n wá ẹni kan ti yoo ṣẹ́ agbara awọn wọnni ti n pọn wọn loju ki o si sọ wọn di orilẹ-ede ti o ni ominira lẹẹkan si i. Nigba naa ni Jesu de ti O si bẹrẹ si i ṣe iṣẹ iyanu pupọ: O n wo awọn alaisan sàn, O n ji oku dide, O n fi iṣu akara marun-un ati ẹja diẹ bọ́ ẹgbẹẹgbẹrun eniyan. Dajudaju O le ṣe ohun gbogbo; a si ri awọn eniyan diẹ ti wọn gba A gbọ́ ti wọn si rò pe Olugbala tabi Messia naa ti dé.

Ṣugbọn lẹyin iwọn ọdun mẹta pere ti o ti n lọ kaakiri laaarin awọn eniyan naa ti o si n ṣe rere, wọn ti kan An mọ agbelebu; wọn si wà labẹ isinru Romu sibẹ. Bi o tilẹ jẹ pe ọpọlọpọ ọkàn ti ri igbala, ti a ti dari ẹṣẹ wọn ji, ti wọn si ti di ominira nipa ti ẹmi; sibẹ wọn n fẹ ki ijọba wọn ni ominira.

Ọrọ naa rú wọn loju, wọn si n wadii laaarin ara wọn pẹlu iyalẹnu: ki ni ṣe ti O fi gbà ki awọn ọta Rẹ̀ na An bẹẹ? Ki ni ṣe ti O fi tẹle wọn lọ si oke Kalfari lati kan An mọ agbelebu? O sa ti sọ pe Oun le pe legioni angẹli lati ran Oun lọwọ bi Oun ba fẹ́. Bi o ba ri bẹẹ, ki ni ṣe ti kò sọkalẹ lati ori agbelebu? Wọn ti ni ireti titi de opin -- ṣugbọn nisisiyii O ti kú.

### Iwe Mimọ́ Ṣẹ

Ọgbẹni kan wa ti orukọ rẹ n jẹ Josẹfu, ara Arimatea, ẹni ti o ti n reti pe ki Ọlọrun gbé ijọba Rẹ kalẹ ninu ayé,o si ni lati mọ pe Jesu ni ipá ninu ijọba naa, bi o tilẹ jẹ pe O ti kú. A ko gbọ nigba kan ri pe oun jẹ́ ọmọ-ẹyin Jesu, ṣugbọn n akoko yii, ko tiju lati tọ Pilati lọ ki o beere oku Jesu ki oun ki o le sin In bi o ti yẹ. Josẹfu jẹ́ ọlọrọ o si ni iboji kan ti o dara ti o fi tọkantọkan fi fun Jesu, nipa bẹẹ o nmu asọtẹlẹ Isaiah ṣẹ: "O si ṣe iboji rẹ̀ pẹlu awọn enia buburu, ati pẹlu ọlọrọ̀ ni ikú rẹ̀" (Isaiah 53:9). Awọn buburu ni awọn ole ti wọn kan mọ'gi pẹlu Kristi. Josẹfu si ni ọlọrọ ninu iboji ẹni ti a sin In si.

### Ni Ọjọ Kẹta

Awọn olori alufaa ti wọn dá Jesu lẹbi ikú ranti pe Jesu ti sọ tẹlẹ pe Oun yoo jinde ni ọjọ kẹta. Wọn ko fi tọkankan gbagbọ pe yoo jinde, ṣugbọn wọn n bẹru pe diẹ ninu awọn ọmọ-ẹyin le yọ́ wa gbé oku Rẹ̀ ki wọn si wi pe O jinde. Wọn fẹ ki Pilatu ri i daju pe o yan iṣọ si iboju naa titi ọjọ mẹta yoo fi kọja ki awọn Ju má ba fọwọ kan An.

Awọn alufaa ki ba ti yọ ara lẹnu nipa awọn ọmọ-ẹyin. Awọn wọnni ko tilẹ ranti mọ pe Jesu ti sọ pe Oun yoo jinde. Inu wọn bajẹ to bẹẹ ti wọn ko le ronu ohunkohun ju pe Jesu olufẹ wọn ti fi wọn silẹ. Ninu ibanujẹ wọn, wọn wi pe: "On li awa ti ni ireti pe, on ni iba da Israẹli ni ìde" (Luku 24:21). Wọn si rò pe nisisiyii gbogbo eyi nì ti pari.

### Ileri Wiwà Laaye

Jesu ti gbiyanju lati sọ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ tẹlẹ pe Oun ni lati jiya ki Oun si kú; ṣugbọn o ti ṣe ileri fun wọn pe Oun yoo tun wà laaye. Akoko kan wa lẹyin ipalarada, ti o sọ fun Peteru, Jakọbu ati Johannu pe ki wọn ma ṣe sọ ohun ti wọn fi oju wọn ri titi igba ti "Ọmọ-enia ba ti jinde kuro ninu okú" (Marku 9:9). Wọn ti ba ara wọn sọ ọ: Ki ni O n sọ nipa jijinde "kuro ninu okú?" Nigba miiran O ti sọ fun wọn pe Oun ni agbara lati fi Ẹmi Oun lelẹ ki Oun si tun gba a; ṣugbọn iru nnkan bẹẹ ko i ti i ṣẹlẹ ri. Bawo ni ọrọ bẹẹ ṣe le ye wọn?

Jesu ti sọ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pẹlu pe lẹyin ti Oun ba ti jinde Oun yoo pade wọn ni Galili. Ṣugbọn awọn ọmọ-ẹyin kò lọ si Galili lati lọ wo O, nitori wọn kò rò lati ri I mọ́.

**Aigbagbọ**

Maria Magdalene ati Maria miiran duro wọn si wo O titi a fi tẹ́ Jesu si iboji Josẹfu, wọn si pada lọ si ile lati lọ wá ikunra ti wọn yoo fi kun Un lara lẹyin ti ọjọ isinmi bá kọja. Wọn ko fi igba kan ronu pe Oun le lọ kuro ki wọn to pada de ibẹ.

Wo o bi o ti yà wọn lẹnu to nigba ti wọn de ni ọjọ kin-in-ni ọsẹ pẹlu ikunra, ti wọn si ba iboji ni ofifo! Jesu ti lọ; ṣugbọn angẹli kan joko nibẹ lati sọ fun wọn pe: " O jinde; kò si nihinyi." Aṣọ ọgbọ daradara nì ti Josẹfu ti ra fun sisin oku Kristi wa nibẹ, nipa eyi iyemeji ko si rara pe ibẹ naa gan an ni a tẹ Ẹ si. Iroyin yii ba awọn obinrin yii lẹru, wọn ko si le gbagbọ.

Jesu ti jinde pẹlu ara ti o ri bi ti eniyan. Nigba ti O pade Maria Magdalene ti O ba a sọrọ ninu ọgba nì, ni akọkọ o ro pe oluṣọgba ni, o si bi i leere bi O ba ti gbé oku Jesu kuro ni ibẹ. Nigba ti O darukọ rẹ , nigba naa ni o mọ pe Oluwa oun ni. O sare pada kankan lati lọ sọ fun awọn ọmọ-ẹyin pe otitọ gidigidi ni pe O jinde kuro ninu oku, oun si ti ri I. Ṣugbọn wọn ko gba a gbọ́.

Nigbooṣe ni ọjọ kan naa, bi meji ninu awọn ọmọ-ẹyin ti n rin lọ si Emmausi, Jesu bẹrẹ si ba wọn rin lọ, O si n ba wọn sọrọ; lẹyin naa O tun duro ba wọn jẹun. Oun ki i ṣe ẹmi bi ko ṣe Jesu gan an funra Rẹ̀, laaye ninu ara. Nigba ti O gbadura si ounjẹ ki wọn to jẹ ẹ, wọn mọ Ọn. O nù mọ wọn loju, bẹẹ ni wọn si pada lẹsẹ kan naa si Jerusalẹmu lati sọ fun awọn Apọsteli pe wọn ti ri Jesu laaye. Ṣugbọn awọn eniyan ti wọn sọ fun kò gbagbọ!

**A Bá Awọn Ọmọ-Ẹyin Wí.**

O ṣe Jesu laanu pe ẹnikẹni ko gbagbọ -- paapaa awọn Apọsteli Rẹ̀ -- titi wọn fi fi oju wọn ri I laaye. O ti sọ fun wọn tẹlẹ pe Oun ni lati kú, ṣugbọn Oun yoo tun jinde ni ọjọ kẹta. Nigba ti Jesu bá awọn mọkanla pade, O beere eredi ti ko fi gba ohun wọnni ti Oun ti sọ fun wọn gbọ́. Pẹlupẹlu ohun wọnni ti awọn wolii ti kọ silẹ nipa Rẹ n kọ́? Wọn ko ha le gba nnkan wọnni gbọ́ bi? O ha yẹ pe ki a fi nnkan hàn wọn ni ojukoju ki wọn to le gbagbọ bi? Jesu sọ fun Tomasi pe: "Nitoriti iwọ ri mi ni iwọ ṣe gbagbọ́: alabukun-fun li awọn ti kò ri, ti nwọn si gbagbọ́" (Johannu 20:29). Ibukun ni wà lori gbogbo awọn ọmọ Ọlọrun ni ọjọ oni ti wọn ko i ti i ri Jesu ninu ara, ṣugbọn ti wọn gbagbọ pe O kú nitori ẹ̀ṣẹ wa O si tun jinde.

**Aṣẹ Kristi**

Jesu sọ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pe Oun ti pari iṣẹ ti Baba fi le Oun lọwọ lori ilẹ aye, ati pe laipẹ Oun yoo pada lọ si Ọrun lati wà pẹlu Baba. Lẹyin ti Oun ba ti lọ, wọn ni lati waasu ohun gbogbo ti Oun ti waasu rẹ̀: ironupiwada ati idariji ẹ̀ṣẹ. Wọn gbọdọ fi kọ́ awọn eniyan pe Jesu fẹran wọn, ati pe wọn ni lati gba A gbọ́ ki a ba le gbà wọn la. Wọn gbọdọ gbagbọ pe Jesu ti kú gẹgẹ bi etutu fun ẹṣẹ wọn O si ti jinde.

Awọn ọmọ-ẹyin ki yoo da wa nikan nigba ti wọn ba n lọ waasu – ni Jerusalẹmu, niwaju awọn ti o pa Jesu; ni Samaria, laaarin awọn eniyan wọnni ti awọn Ju korira; ni gbogbo agbegbe yi kaakiri; ati niwaju oniruuru ajeji eniyan titi de opin ilẹ ayé. Jesu yoo ba wọn lọ, yoo si ba wọn ṣiṣẹ lati maa "fi idi ọ̀rọ na kalẹ." Itumọ eyi ni pe Oun yoo bukun iṣẹ-iranṣẹ wọn; yoo si gba ọkàn la, yoo wo awọn alailera sàn ni idahun si adura wọn, gẹgẹ bi O ti ṣe ileri.

**Awọn Ami Ti N Tẹle e**

Jesu wi pe: "Àmi wọnyi ni yio si ma ba awọn ti o gbagbọ́ lọ." Ọpọlọpọ eniyan ni wọn n sọ lọjọ oni pe akoko iṣẹ-iyanu ti kọja; pe awọn iṣẹ-iyanu ṣẹlẹ ni igba laelae nitori ki a ba le fi idi ijọ mulẹ ni, ko tun si iṣẹ iyanu mọ́ nitori a ko ni ilo wọn mọ́. Ṣugbọn Jesu wi pe : "Àmi wọnyi ni yio si ma ba awọn ti o gbagbọ́ lọ; Li orukọ mi ni nwọn o ma le awọn ẹmi èṣu jade; nwọn o si ma fi ède titun sọ̀rọ; nwọn o si ma gbé ejò lọwọ; bi nwọn ba si mu ohunkohun ti o li oró, ki yio pa wọn lara rara: nwọn o gbé ọwọ́ le awọn olokunrun, ara wọn ó da." Bi awọn ami wọnni ko ba tẹle igbesi-ayé igbagbọ́ wa, o ni lati jẹ pe a kò gbagbọ ni; "li aisi igbagbọ́ ko ṣe iṣe lati wù u" (Heberu 11:6).

Bi awọn alaisan kò ba ri iwosan ni idahun si adura wa, bi igbesi-ayé awọn ẹlẹṣẹ ko ba si yipada nipa iṣẹ-iranṣẹ wa, o ni lati jẹ pe ikuna kan wa ninu igbagbọ́ wa ni. Jakọbu Apọsteli kọ akọsilẹ pe "fi igbagbọ́ rẹ hàn mi li aisi iṣẹ, emi o si fi igbagbọ́ mi hàn ọ nipa iṣẹ mi" (Jakọbu 2:18). Ni ọrọ miiran bi iwọ ba sọ pe o ni igbagbọ́; fi hàn nipa iṣẹ rẹ gẹgẹ bi awọn ileri Ọlọrun. Ọrọ Ọlọrun ko le kuna, awọn ileri Rẹ si jẹ ti awọn ti o ba gbagbọ́.

Jesu gbadura fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ pe ki igbagbọ́ wọn ma ṣe yẹ. Bi a ba n ka Bibeli ti a si n gbadura si Jesu, Oun yoo fun wa ni igbagbọ́ ti a oo fi ṣe iṣẹ aṣeyọri fun Ọlọrun. Ṣiwaju, a gbọdọ dari ẹ̀ṣẹ wa ji wa; nigba naa bi ọkan wa ko ba da wa lẹbi, awa ni igboya pe Ọlọrun n gbọ ti wa nigba ti a ba gbadura, a o si ri idahun gbà. "Àmi wọnyi ni yio si ma ba awọn ti o gbagbọ́ lọ," wà ninu awọn ọrọ ti Jesu sọ kẹyin. Lẹyin naa ni O wá paṣẹ fun wọn ki wọn pada si Jerusalẹmu ki wọn si duro de ifiwọni Ẹmi Mimọ́, eyi ti yoo fun wọn ni agbara lati jẹri nibikibi ti wọn ba lọ. Igbagbọ wọn yoo tun ga si i ju bẹẹ lọ to bẹẹ ti ami yoo maa tẹle iwaasu wọn.

**Si Inu Awọsanma**

Ohun gbogbo ti pari nisisiyii. Fun ogoji ọjọ ni Jesu ti rin pẹlu wọn, O si ti fun wọn ni ẹri pupọ ti ko ṣe e ṣe iyemeji rẹ̀ rara pe Oun tun wa laaye ni tootọ, ani Jesu naa gan an ti o ti kú lori agbelebu. Nibẹ ni ori Oke Olifi, bi awọn ọmọ-ẹyin ti tẹju mọ Ọn, a gba Jesu soke sinu awọsanma lọ si Ọrun -- bẹẹ ni O si lọ.

Awọn ọmọ-ẹyin duro nibẹ pẹlu iyanu, wọn si tẹju mọ ọgangan ibi ti Jesu ti nù mọ́ wọn loju. Njẹ ireti wọn tun parẹ lẹẹkan si i? Njẹ Ẹni ti wọn fẹran tọkantọkan to bẹẹ ti lọ titi lae ni yẹn? Lojiji awọn angẹli meji duro laaarin wọn, wọn si wi pe: "Jesu na yi, ti a gbà soke ọrun kuro lọwọ nyin, yio pada bẽ gẹgẹ bi ẹ ti ri i ti o nlọ si ọrun." Eyi ni jẹ ileri pe Oun yoo tun pada wá, o si tẹ awọn ọmọ-ẹyin lọrun. Lai si anini, wọn ranti nisisiyii pe Jesu ti sọ pe: " Nitori emi nlọ ipèse àye silẹ fun nyin. Bi mo ba si lọ ipèse àye silẹ fun nyin, emi o tún pada wá, emi o si mu nyin lọ sọdọ emi tikarami; pe nibiti emi gbé wà, ki ẹnyin le wà nibẹ pẹlu" (Johannu 14:2, 3).

Jesu n sọ eyi fun wa pẹlu gẹgẹ bi Onigbagbọ ni ọjọ oni. O wà ni Ọrun o n pese àyè silẹ fun wa, O si n mura wa pẹlu silẹ fun àyè naa; ni ọjọ kan lai pẹ jọjọ Oun yoo tun pada wa, yoo si mu awọn eniyan Rẹ lọ si Ọrun nibi wọn yoo jẹ adun gbogbo ibukun iyanu wọnni ti O ti pese silẹ fun awọn ti o fẹran Rẹ̀.

Nisisiyii a gbọdọ mura si iṣẹ Oluwa tọkantọkan, ki a si maa fi igbagbọ wa ninu Rẹ̀ hàn nipa iṣẹ ti a n ṣe.

## AWỌN IBEERE

1. Ta ni kan Jesu mọ'gi? Ki ni ṣe?
2. Ta ni sinku Jesu? Asọtẹlẹ inu Iwe Mimọ́ wo ni o mu ṣẹ?
3. Bawo ni a ṣe mọ pe awọn Maria mejeeji ko gbagbọ pe Jesu yoo tun jinde?
4. Bawo ni ọna ti awọn ọmọ-ẹyin fi gba iroyin pe Jesu tun wa laaye ti ri lọkan Rẹ̀?
5. Sọ diẹ ninu awọn igba ti Jesu fara hàn lẹyin ti O jinde.
6. Sọ diẹ ninu awọn ọrọ ikẹyin Jesu.
7. Awọn wo ni yoo gba ibukun ti Jesu ṣe ileri?
8. Ọna wo ni Jesu gba fi ayé yii silẹ?
9. Ki ni iṣẹ ti awọn angẹli ti wọn yọ si awọn ọmọ-ẹyin lori Oke Olifi jẹ́ fun wọn?